FUJAH/Vol. 2, No. 1 | June 2025 | Pages 172– 184

# Ìṣẹ̀lẹ̀ Ajẹmọ́-Àwùjọ Òde-Òní nínú Ewì J.F. Ọdúnjọ

**Abosede, Olayinka Adeyanju**
Department of Linguistics and African languages
Emmanuel Alayande university of Education, Oyo.
adeyanjuabosede73@gmail.com

**SULAIMAN,** Fatai
Department of Yorùbá Studies,
Tai Solarin University of Education,
Ìjagun, Ìjẹ̀bú-Òde, Ogun State, Nigeria.
+2347063900080
olaitonolaide2018@gmail.com

**Àṣamọ̀**

*Ohun tí iṣẹ́ yìí dá lé ni Ìṣẹ̀lẹ̀ Ajẹmọ́-Àwùjọ Òde-Òní nínú Ewì Joseph Fọláhàn Ọdúnjọ . Àwọn onímọ̀ tí wọ́n ti ṣe iṣẹ́ lórí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ nínú ewì kò tíì ṣe àyẹ̀wò ìjẹyọ rẹ̀ nínú ewì Joseph Fọláhàn Ọdúnjọ. Nínú ewì Ọdúnjọ, a wò ó bí ó ṣé ń gbé ewì rẹ̀ lé oríṣìíríṣìí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Ọgbọ́n ìwádìí tí a lò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí ni ìlànà ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò tí a ṣe pẹ̀lú awọn onímọ̀ tí wọ́n ti ṣe iṣẹ́ lórí iṣẹ́-ọnà Ọdúnjọ rí. Yàtọ̀ sí èyí, a tún ka onírúurú ìwé tí ó ti kọ bí i Aláwìíyé apá kìn-ín-ní títí kẹ́fà pàápàá jù lọ ìwé ewì rẹ̀* ***Àkójọpọ̀ Ewì Aládùn****. Ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, bí àwọn akéwì-akọ̀wé bá túnbọ̀ gbájúmọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ nínú iṣẹ́-ọnà pàápàá jù lọ nínú ewì, àwùjọ yóò ní ìdàgbàsókè tí ó péye ní gbogbo abala tí àwùjọ pín sí.*

**Kókó-Ọ̀rọ̀:** Lítíréṣọ̀, Ewì, Joseph Fọláhàn Ọdúnjọ, Àwùjọ, Yorùbá.

**Ìfáárà**

A kò le tún ṣẹ̀ṣẹ̀ máa ṣe àwíjàré pé ọ̀kan lára àwọn lítíréṣọ̀ Yorùbá ni ewì jẹ́. Èyí kò sẹ̀yìn èrò ìjinlẹ̀ Yorùbá tó máa ń kún fọ́fọ́ sí inú ewì yálá ewì ìgbàlódé tàbí ewì àbáláye tí méjèèjì lè jẹ́ àpilẹ̀kọ tàbí alohùn. Èyí gan-an ló bí àyẹ̀wò àwọn kókó-èrò tí ó jẹ mọ́ èrò-ìjìnlẹ̀ Yorùbá tí a yẹ wò nínú àṣàyàn ewì tí ó wà nínú *Ewì Aládùn* tí Joseph Fọláhàn Ọdúnjọ kọ. A ṣàkíyèsí pé ewì kíkọ jẹ́ àkóyawọ̀ ẹ̀bùn àtinúdá, ìmísí, ẹ̀bùn èdè, àfọkànsí àti èrò-ìjìnlẹ̀ nípa àyíká àti àkíyèsí nípa àwùjọ, (Ọ̀pádọ̀tún 2003:56). Gbogbo èyí ni a rò papọ̀ tó mú wa gùn lé àgbèyẹ̀wò kókó-èrò tí ó jẹ mọ́ èrò-ìjìnlẹ̀ Yorùbá tí ó ṣú yọ nínú *Ewì Aládùn* tí Joseph Fọláhàn Ọdúnjọ kọ. Ọdúnjọ jẹ́ ọ̀mọ̀ràn, amòye, amẹ̀ṣọ-ọ̀rọ̀, òǹpèdè nínú àwọn tí wọ́n pilẹ̀ ewì ìgbàlódé tí wọ́n ń pè ní àwọn akéwì-akọ̀wé.

**Ta a ni Ọdúnjọ**

Ní ọdún 1904 ni ìwádìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé wọ́n bí Joseph folahan Ọdúnjọ sí ìlú Abẹ́òkúta ní agbègbè ìbarà. Ilé - ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí st. Augustine primary school " ní ìlú Abẹ́òkúta ni ó lọ. Lẹ́yìn èyí ni ó lọ sí ilé - ẹ̀kọ́ gírámà ti ìjọ àgùdà ìyẹn ti Catholic Higher Elementary Training school. Lẹ́yìn èyí ni ó lọ sí ìlú London láti lọ sí ilé - ẹ̀kọ́ olùkọ́ kan ìyẹn" London Institute of Education. Lẹ́yìn tí Ọdúnjọ dé láti london tí ó lọ ni ó mú iṣẹ́ Olùkọ́ni ní òkúkúdùn. Ní ilé - ìwé Catholic Traning College Ìbàdàn láààrín ọdún 1924 sí 1927, lẹ́yìn tí ó tí wá di ọ̀gá àgbà fún ilé - ẹ̀kọ́ rẹ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ tí ó ti jáde tẹ́lẹ̀ rí, ìyẹn "St Augustine Primary School ni Abẹ́òkúta. Ọdúnjọ ni ó jẹ́ olùdásílẹ̀ ẹgbẹ́ - ìṣọ̀kan àpapọ̀ àwọn olùkọ́ nínú ìjọ Kátólíìkì láti lè máa jíròrò pẹ̀lú àwọn aláṣẹ àti àwọn olóòtú sọ̀rọ̀ lórí ètò ìdàgbàsókè àwọn olùkọ́. Bákan náà ni Ọdúnjọ tún ṣe iṣẹ́ olùkọ́ káàkiri pàápàá jù lọ àwọn ilé - ẹ̀kọ́ ìjọsìn àwọn Kátólíìkì ní orísìírísìí láààrín ọdún

1940 sí 1950. Ọdúnjọ jẹ́ ẹ̀dá tí ó nífẹ̀ẹ́ sí àṣà, èdè àti ìṣe Yorùbá, èyí jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ohun tí ó jẹ́ kó nífẹ̀ẹ́ sí kíkọ àwọn ìwé ní èdè Yorùbá ní orísìírísìí yálà ewì ni, ìtàn àròsọ, tàbí eré-oníṣe. Kódà ìwádìí fi hàn pé, ìwé eré-oníṣe Agbàlọ̀wọmẹ́rìí Báalẹ̀ Jòǹtolo tí Ọdúnjọ gbé jáde ní ọdún 1958 jẹ́ gbòógì nínú eré - oníse ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ní èdè Yorùbá. Nígbà tí ó di ọdún 1966 sí ọdún 1969 ni Ọdúnjọ jẹ́ ọ̀kan lára ìgbìmò àwọn ẹgbẹ́ akọ́mọlédè tí wọ́n èyí tí wọ́n ṣiṣẹ́ lórí àkọtó èdè Yorùbá. Ọdúnjọ tún jẹ́ ọ̀kan lára omo ẹgbẹ́ olùkọ́ orílẹ̀ èdè Nàìjíríà (Nigeria Union of Teachers) láàárín ọdún 1942 sí 1951 ni Ọdúnjọ jẹ ọmọ ẹgbẹ́ olùkọ́ ní ilé Naijiria Bákan náà nígbà tí ó di ọdún 1942 sí 1951 ni ọdúnjọ jẹ Ààrẹ ẹgbẹ́ àwọn ọmọ bíbí ìlú Ẹ̀gbádò Yewa tí ẹ̀ka Èkó. Nígbà tí ó di ọdún 1951ni JF Ọdúnjọ dibò tí ó sì wọlé sí ilé asòfin ẹkùn ìwọ̀ - oòrùn Nàìjíríà kí ó tó di pé wọ́n yàn-àn gẹ́gẹ́ bíi minisita fún òrọ ilé àti òṣìṣẹ́ ilẹ̀ Nàìjíríà. Díẹ̀ lára àwọn ìwé tí Ọdúnjọ kọ ni

Aláwìíyé fún àwọn ilé - ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ 1943 Ọmọ òkú ọrùn 1964 Kúyẹ̀ 1978

Àkójọpọ̀ Ewì Aládùn 1961

**Ìtumọ̀ Ewì**

Onírúurú onímọ̀ ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí ewì Yorùbá. Àwọn onímọ̀ kan gbìyànjú láti fún ewì ní oríkì, àwọn kan pààlà láàrin ewì alohùn àti ewì àpilẹ̀kọ. A tún rí ọ̀pọ̀ nínú àwọn onímọ̀ yìí, tí wọ́n ṣe iṣẹ́ lórí ìpínsísọ̀rí ewì Yorùbá. Ìwé atúmọ̀ èdè-ewì *(Encylopaedia of Poetry)* (1999), vol. 22: 27 náà sọ̀rọ̀ nípa ewị báyìí:

Poetry differs from prose in several significants respects. Both may employ the same emotions, but poetry usually is more intense, less directive, more suggestive and ambigious. Both prose and poetry have rhythm, in poetry is more marked and regular.

(Ewì yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ geere ní oríṣìírìṣìí ọ̀nà. Ó ṣe é ṣe kí àwọn méjèèjì ṣe àmúlò kókó-èrò kan náà, kí wọ́n sì gbìyànjú láti fi ìmọ̀lára kan náà hàn. Ṣùgbọ́n, ewì máa ń kún fún pọ́n-ọ́n-na nínú àgbékalẹ̀ rẹ̀. Ìwọ́hùn wà nínú ọ̀rọ̀ geere àti ewì, ṣùgbọ́n ìwọ́hùn inú ewì máa ń hànde jù, a sì máa wá léraléra ju ti inú ọ̀rọ̀ geere lọ).

Nínú àyọlò òkè yìí, a ri pé onímọ̀ náà ṣe àfihàn ìyàtọ̀ tó wà láàrin ewì (alohùn tàbí àpilẹ̀kọ) pẹ̀lú àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ mìíràn. Ewì ni ohun tí a fi àrògún àti àròjinlẹ̀ ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Ewì lè jẹ́ kíkọ sílẹ̀, sísọ lẹ́nu, sùgbọ́n ohun tí ó ṣe pàtàkì jù lọ ni pé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìdániláraya ni ewì máa ń dá lé.Bákan náà sì ni pé, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ní ọlọ́kan-ò-jọ̀kan ni àwọn akéwì máa ń gbé iṣẹ́-ọnà wọn kà.

**Ìṣẹ̀lẹ̀ Ajẹmọ́-Àwùjọ Òde-Òní nínú Ewì JF Ọdúnjọ**

I. Ìkìlọ̀ Ìwà Ìbàjẹ́ Láwùjọ.

II. Pàtàkì Ọmọ Bíbí Láwùjọ Yorùbá.

III. Ẹ̀kọ́ Nípa Ewu Ìkóbìnrinjọ.

IV. Ipò Pàtàkì Tí Ẹ̀kọ́ Ìwé Wà

V. Pàtàkì Owó Níní Ní Ìgbé Ayé Ẹ̀dá

**Ìkìlọ̀ Ìwà Ìbàjẹ́ Láwùjọ.**

Bí epo kínńkín lára aṣọ àlà, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ìwà ìbàjẹ́ rí nínú àwùjọ. Kò sí bí ènìyàn se lè gbìyànjú láti fi pamọ́, yóò ṣì fojú hàn kedere náà ni. Àwọn akéwì gẹ́gẹ́ bí i òjíṣẹ́ àti aríran sábà máa ń fi ewì wọn jẹ́ iṣẹ́ sí àwọn tí ó ń hu àwọn ìwà tí kò bójúmu wọ̀nyí láti dẹ́kun rẹ̀ kí ó má ba à kó ẹrẹ̀ bá àwùjọ, ṣé èéfín ni ìwà, yálà rere tàbí búburú torí kò ṣe é fi pamọ́ lọ títí. Ìdí tí àwọn akéwì ṣe máa ń tẹpẹlẹ mọ́ ṣíṣe ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ ni pé bí a ṣe ń gbìyànjú láti jẹ èkuru rẹ̀ kó tán, bẹ́ẹ̀ ni àwọn kan tún ń gbọn ọwọ́ rẹ̀ sínú àwo, àgbàrá òjò tó ṣe tán láti gbé ilé ni, onílé ni kò ní gbà fún wọn; ṣé kankan báyìí là ń ran fádití. Ìdàgbàsókè ni Ọdúnjọ máa ń tẹlẹmọ́ jù lọ nínú iṣẹ́-ọnà rẹ. Ìlò ìkìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ sì jẹ́ ọ̀nà ìdàgbókè kan pàtó tí Ọdúnjọ fí máa ń ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn ènìyàn àwùjọ. A rí àpẹẹrẹ ìkìlọ̀ ìwà ibàjẹ́ yìí nínú àwọn ewì Ọdúnjọ, ó bá ọmọdé wí, ó bá àgbà wí, bẹ́ẹ̀ sì ló tún jẹ́ ká mọ àwọn àǹfààní tí dídẹ́kun irú àwọn ìwà òdì bẹ́ẹ̀ máa ń ṣe àwùjọ lápapọ̀. Nínú ewì “Tọ́jú Ìwà Rẹ”, ó ní:

“Tọ́jú ìwà rẹ, ọ̀rẹ́ mi

Ọlá a máa ṣí lọ nílé ẹni

Ẹwà a sì máa ṣì lára ènìyàn”

(Ojú Ìwé 2, ìlà 1-3)

Akéwì fi ewì rẹ̀ òkè yìí gbé ìwà borí ọlá àti ẹwà, ó jẹ́ ká mọ̀ pé kò sí irú ẹwà tàbí owó tí ènìyàn lè ní láyé, bí kò bá ní ìwà, asán ni. Ó tẹ̀ síwájú báyìí pé:

“Bí o lówó bí o kò níwà ńkọ́

Ta ní jẹ́ finú tán ọ bá ṣohun rere?

Bí o sì jẹ́ obìnrin rọ̀gbọ̀dọ̀

Bí o bá jìnnà síwà tí ẹ̀dá ń fẹ́

Ta ní jẹ́ fẹ́ ọ sílé bí aya?

Tàbí bí o jẹ́ oníjìbìtì ènìyàn

Bí o tilẹ̀ mọ ìwé àmọ̀dájú

Ta ní jẹ́ gbéṣẹ́ ajé fún ọ ṣe?”

(Ojú Ìwé 2, ìlà 10-17)

Ohun tí akéwì fẹ́ ká mọ̀ nínú àyọlò òkè yìí ni pé, ìwà ni olúborí ìgbésí ayé ẹ̀dá. Bí ìwà ènìyàn bá dára, ohun gbogbo a máa dùn fun, ìgbé ayé tó rọrùn ni yóò sì máa gbé torí ìwà rere tí ó bá ń hù ni yóò máa mú ayé dẹrùn fún un. Ṣùgbọ́n tí ó bá jẹ́ ẹni tí kò níwà, àwọn nǹkan yòókù tí ó bá ń ṣe yóò máa mú ìnira díẹ̀díẹ̀ lọ́wọ́. Béèyàn lówó tí ò níwà, ọmọ aráyé á kọ̀ máa bá a lá ọwọ́ epo rẹ̀ lásán ni, wọn ò jẹ́ fi tinútinú bá a ṣe. Bó bá sì jẹ́ obìnrin tó rẹwà tó dùn ún wò tó sì tún ní gbogbo nǹkan tí ọmọbìnrin fi ń ṣe oge, bí ìwà rẹ̀ kò bá dára, àlòpatì nirú u wọn máa ń dà. Kò sí ọkùnrin tó máa fẹ́ wọn sílé bí aya. Ọdúnjọ fẹ́ ká mọ̀ pé kò sí irú ẹwà, owó, ọlá, iyì, ẹ̀bùn tàbí ọgbọ́n tí ènìyàn lè ní, bí kò bá fi ìwà rere kún un yóò kábàámọ̀ nígbẹ̀yìn. Nínú ewì “Ìwà àfọwọ́fà”, akéwì jẹ́ ká mọ̀ pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìṣòro tí àwa ẹ̀dá ń kojú láyé, èyí tí a fi ọwọ́ ara wa fà ló pọ̀jù nínú wọn. Akéwì tọ́ka àpẹẹrẹ àwọn ìwà àìnítẹ̀lọ́rùn àti etí kunkun tí àwọn ènìyàn máa ń jù tàbí kọ sí ohun tí ó lè ṣe wọ́n ní àǹfààní. Ó ní:

“Ẹ̀dá tí yio bá fàjàngbàn

Bí o bá dá a lẹ́kun ṣé kò ní gbọ́

Ohun tó ń fẹ́ ṣe ní i ká a lára”

(Ojú Ìwé 15, ìlà 1-3)

Béèyàn bá máa fi ọwọ́ ara rẹ̀ ṣera rẹ̀, tí òun náà sì mọ̀ pé ohun tí òun fẹ́ ṣe yóò padà bu ú lọ́wọ́, ṣùgbọ́n nítorí agídí àti ìwà tinúmi-ni-n-ó-ṣe, bẹ́ ẹ bá wí fún un kò ní gbọ́, ó dìgbà tó bá fa ìjọ̀gbọ̀n náà sọ́rùn ara rẹ̀, tí ọ̀rọ̀ dojúrú pátápátá kó tó mọ̀ pé nǹkan ti ṣe òun. Bá a bá ń gba òròmọdìẹ lọ́wọ́ ikú, kò kúkú ní mọ̀, àròyé pé wọn ò jẹ́ kí òun lọ jẹ lákìtàn ni yóò máa ṣe nínú ara rẹ̀. Akéwì tẹ̀ síwájú, ó ní:

“Àyé gba èkùlù ọ̀dàn

Ó ń fẹ́ nípọn láyà bí ìrá

Olówó jẹun yó tán ó ń wákú kiri

Ìrẹ̀ yó tán ó bẹ́ra rẹ̀ níkùn

Aya yó tán ó ń lé bebe sọ́kọ

Àyé gbàwọ̀fà tán

Ó ń pe olówó rẹ̀ ní wèrè

Ọmọ yó tán ó ń pe baba lẹ́ranko”

(Ojú Ìwé 15, ìlà 4-11)

Bí àwọn ènìyàn ṣe máa ń fi ayọ̀ fọ́ nǹkan lójú pọ̀ ni akéwì ṣe lálàyé fún wa nínú àyọlò òkè yìí. Béèyàn bá jẹun yó tán ṣe ló yẹ kó gbé jẹ́ kó má nàgà sí ohun tí ọwọ́ rẹ̀ kò tó, ṣùgbọ́n èyí kò sí fún àwọn ẹ̀dá kan. Bẹ́ẹ̀ alágẹmọ tó ń ṣe jẹ́jẹ́ ikú ń pa wọ́n, bèlèǹtàsé ọ̀pọ̀lọ́ tó ń janra rẹ̀ mọ́lẹ̀ káàkiri. Ó tẹ̀ síwájú, ó ní:

“Ọmọ iná ní í wọná lọ fúnra wọn

Tàbí ẹ kò mọ̀ pé ìṣẹ́ kìí wá ènìyàn

Ẹni tó ń lọ wáṣẹ́ẹ̀ ló ń fẹ́yọnu

Òṣì ń ta ajá ó ń po ara rẹ̀ méérú

Òṣì ń ta ẹ̀wù àlà ó ń bépo wọ̀yá ìjà

Òṣì ń ta ẹlẹ́dẹ̀ ó fara ṣe èkuru délẹ̀ jìgbìnnì

Olúwa kó ṣọ́ni lọ́wọ́ orí inú ẹni

Àfọwọ́fà ní í fòṣì tẹ̀dá

Ikú tó ń pa olúkálukú láyé

Ó ń bẹ lọ́rùn ara wọn"

(Ojú Ìwé 15, ìlà 18-23)

Ẹni tí Ọlọ́run bá ti gbà fún ti bọ́ sáyé. Béèyàn bá ti ní ìtẹ́lọ́rùn , dandan ni kó ráyé gbé. Ojúkòkòrò àti àìnítẹ́lọ́rùn ló máa ń ti ènìyàn láti tọwọ́ bọ nǹkan tó lè pa á lára tàbí ṣe é ní ìjàǹbá. Nígbà tí ọ̀bẹ bá gé ọmọ lọ́wọ́ tán ni yóò tó mọ̀ pé eré e géle lòun ń fi abẹ ṣe. Akéwì ń fẹ́ ká mú ìwà àìnítẹ́lọ́rùn kúrò, bọ́kàn bá ti balẹ̀ níwọ̀nba, kò sí ohun tó yẹ kéèyàn tún máa wá kiri mọ́. Àfọwọ́fà ló ń kó òṣì bá ẹ̀dá, ká ṣọ́ra ká má fọwọ́ ara ẹni ṣera ẹni. Akéwì yìí tún tẹ̀ síwájú láti jẹ́ ká mọ̀ pé olè jíjà àti ìwà ọ̀kanjúà kò yẹ ọmọlúàbí. Kìí ṣe ìwà tó yẹ ká máa bá lọ́wọ́ ẹni tàbí kẹ́ni máa hù láwùjọ. Ṣé àdàpè olè ni ọmọ mi ń fẹ́wọ́, àgbà tó bá sì ń yọ́lẹ̀ dà, ohun burúkú a máa yọ́ irú u wọn ṣe. Nínú ewì "Kí ni ng ó folè ṣe", akéwì ní:

"Kí ni ng ó folè ṣe láyé tí mo wá?

Kí ni ng ó folè ṣe láyé tí mo wá

Láyé tí mo wá kàkà kí ng jalè

Kàkà kí ng jalè ma kúkú dẹrú

Kí ni ng ó folè ṣe láyé tí mo wá?"

(Ojú Ìwé 41, ìlà 1-5)

"Ẹni tó jalè á délé ẹjọ́

Ẹni tó jalè á délé ẹjọ́

Adájọ́ á wá fẹ̀wọ̀n sí i lẹ́sẹ̀

Fẹ̀wọ̀n sí i lẹ́sẹ̀ bí olúgbẹ̀ẹ́

Ẹní bá jalè á délé ẹjọ́"

(Ojú Ìwé 41, ìlà 6-10)

Ìwà tó lòdì sí ti ọmọlúàbí pátápátá ni olè jíjà, ìwà tí ó máa ń dójútini tó sì tún máa ń tàbùkù bá ènìyàn ni pẹ̀lú. Akéwì jẹ́ ká mọ̀ pé béèyàn bá ń ṣe ẹrú dípò olè jíjà, ó sàn gidi. Olè jíjà ò da nǹkan fún, ó ń bani lórúkọ jẹ́ ni, ìwà burúkú gbáà ni, bọ́wọ́ bá tẹ irú u wọn, ilé ẹjọ́ ni wọ́n ti ń dajọ́ ẹ̀wọ̀n fún wọn. Kò sí bí onítọ̀hún ṣe lè dára tó, ọ̀rọ̀ irú wọn ò yàtọ̀ sí ti ẹni tó jalè lẹ́ẹ̀kan tó wá daṣọ àrán borí; aṣọ olè ló dà bora. Olè ni olè ń jẹ́ kò lórúkọ méjì.

Akéwì tún gbà wá níyànjú pé ká má bá olè da nǹkan pọ̀ bí a bá ti ṣàkíyèsí pé olè ni ẹni náà, ó ní ká yẹra fún irú ẹni bẹ́ẹ̀ ló tọ́. Ṣé ikú boni láṣìírí ju olè jíjà lọ.

"Ẹ̀wọ̀n kò sunwọ̀n fọ́mọlúàbí

Ẹ yé ẹ má bólè ṣe ẹgbẹ́ tí mo ní"

(Ojú Ìwé 41, ìlà 19-20)

"Olúwa má folè ṣe ẹni tí a ní

Ẹni tí a ní kànràn kó jalè

Kànràn kó jalè bó bá kú ó tọ́

Olúwa má folè ṣe ẹni tí a ní"

(Ojú Ìwé 42, ìlà 22-25)

Nínú ewì "Ìwà Ọ̀kanjúwà kò dára" ni akéwì ti kìlọ̀ ìwà yìí pẹ̀lú ìtàn àwọn ọ̀rẹ́ méjì kan tí wọ́n ń ṣòwò àjàṣẹ́. Wọ́n ríṣe gidi látara òwò tí wọ́n ń ṣe, wọ́n ralẹ̀, wọ́n kọ́lé, wọ́n sì tún lẹ́nu láàárín ẹgbẹ́. Bùkọ́lá àti Bùkóyè ni orúkọ àwọn méjèèjì.

"Ẹ̀yin kò fọ̀rọ̀ ìtàn

Tí ng ó sọ sílẹ̀ yìí ṣàríkọ́gbọ́n

Kí ẹ múra sísẹ̀, kí ẹ yé fẹ́wọ́ kiri

Ṣé ọ̀rẹ́ méjì ló pàmọ̀ pọ̀

Tí wọ́n ń ṣòwò àjàṣẹ́ ní níná

Tí wọ́n dẹni ní lááríí lójú ayé gbogbo

Ọ̀kan Bùkọ́lá, ọ̀kan Bùkóyè

Wọ́n jọ ń ṣohun gbogbo tí wọ́n ń ṣe"

(Ojú Ìwé 43-44, ìlà 19-26)

Ìwà ọ̀kánjúà àti àìnítẹ́lọ́rùn ló ti Bùkọ́lá tó fi lọ nàgà fa ohun tó kó bá a.

"Bùkọ́lá wá wò sùnsùn

Pé owó wọ̀nyí kò tó ná mọ́

O ronú sóhun tó máa ṣe

Ṣé báyè bá gbèkùlù ọ̀dàn

A máa fẹ́ nípọn láyà bí ìrà

Bólówó jẹun yó tán, a máa wákú kiri"

(Ojú Ìwé 44, ìlà 36-41)

Níbi tó ti ń wá sogúndogójì kiri ló ti kó sọ́wọ́ àwọn oníjìbìtì tí wọ́n gba gbogbo owó ọwọ́ rẹ̀ tán tí wọ́n sì já a sí kolobo. Iwájú ò ṣe é lọ mọ́, àti padà sẹ́yìn di ìtìjú ńlá, ló bá bẹ̀rẹ̀ sí ní kólé onílé kiri ibẹ̀ ni ọwọ́ àwọn Ọlọ́pàá ti tẹ̀ ẹ́, ó dèrò ẹ̀wọ̀n tó ń faṣọ péńpé roko ọba.

"Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ ó dọlọ́ṣà tó ń ṣọ̀ṣọ́lẹ̀

Ó dẹni tó ń kólé onílé kiri

Ó dèrò tó ń já ọlọ́kọ̀ ní wá-ńgọ̀nù

Lójú irin tó ń lúgọ sí kiri

Ọ̀rọ̀ yìí wá pọ̀ lápọ̀jù

Ó dohun tí Ọlọ́pàá fàáké kọ́rí

Tí wọ́n ṣọdẹ tọ́wọ́ fi tó jagun

Tó dèrò tí wọ́n jù sẹ́wọ̀n

Tó ń gé koríko nínú ilé Ọba"

(Ojú Ìwé 44-45, ìlà 57-65)

Akéwì fi ewì yìí sọ ìtàn láti fi kọ́ wa pé ìwà ọ̀kanjúà ò dára tó. Béèyàn bá wà tí kò ní àmójúkúrò, tí ohun gbogbo ń ṣe múwámúwá lójú rẹ̀, ibi tí ó máa ń padà kángun sí fún irú wọn kìí dára rárá.

"Ṣé ẹni tí díẹ̀díẹ̀ kò bá kún lójú

Ohun tó ní a tún a tún lọ tán porogodo

Ìwà ọ̀kánjúwà ló ń fòṣì tẹ̀dá

Ká jóhun ẹni ó máa tó lójú ẹni"

(Ojú Ìwé 45, ìlà 66-69)

**Pàtàkì Ọmọ Bíbí Láwùjọ Yorùbá.**

Akéwì ṣàfihàn ọmọ gẹ́gẹ́ bí i igi-lẹ́yìn-ọgbà, Àrólé, Kòṣeémánìí àti ọjọ́ ọ̀la ẹni. Ó jẹ́ ká mọ̀ pé kò sóhun tí ènìyàn lè fowó rà láyé tó lékè ọmọ. Bí ẹ̀dá bá wà tí kò bá lọ́mọ láyé bí ìgbà tó wáyé asán ni. Ọmọ ṣe pàtàkì, ọmọ ṣe kókó. A rí àpẹẹrẹ kókó ọ̀rọ̀ yìí nínú ewì "Ọmọ ni ìgbẹ̀hìn ọlà", ó ní:

"Ọmọ nìgbẹ̀hìn ọlà

Ọmọ làrà, ọmọ lẹ̀yẹ

Bí a bú ni lẹ́hìn bá ò gbọ́

Ṣé ọmọ ẹni ní í sọ ọ́ fún ni

Kí la tún ń fowó rà

Tí ó lékè ọmọ?

Iná kú ó feérú bojú

Ọ̀gẹ̀dẹ̀ kú ó fọmọ rẹ̀ rọ́pò

Bí aládi kò sí nílé

Ọmọ ní í jogún ẹbu

Ọmọ ni yóò jogún ẹwà lọ́dọ̀ wa”

(Ojú Ìwé 5, ìlà 1-11)

Akéwì ń jẹ́ ká mọ̀ pé béèyàn bá lọ́lá láyé, tó kó ọrọ̀ jọ, tó sì tún ní ohun àlùmọ́nì lóríṣiríṣi, bó pẹ́ bó yá a máa dàgbà darúgbó fayé sílẹ̀ lọ, àwọn ọmọ tí ó bá bí ni yóò jogún gbogbo ohun ìní rẹ̀ tí wọn yóò sì máa fi ṣe ẹ̀yìn rẹ̀ ní dáadáa. Bó bá jẹ́ ẹni tí kò fọmọ sáyé lọ, àwọn ọmọ ọlọ́mọ ni yóò jogún gbogbo ohun ìní rẹ̀ tàbí kí gbogbo ẹ̀ ṣègbé dànù.

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ‘Ọmọ bẹẹrẹ, òṣì bẹẹrẹ', Akéwì tún fi ìdí ọ̀rọ̀ yìí múlẹ̀ nínú ewì rẹ̀ kan tó pè ní “Ọmọ Àtàtà”. Ó jẹ́ ká mọ̀ pé kò dìgbà tí ènìyàn bá bímọ jọ kalẹ̀ bí ẹdá kó tó lè sọ pé òun bímọ, bí ó bá ṣe tọ́ ọmọ sí ni yóò ṣe gbádùn ọmọ. Ṣé ọmọ tá à bá kọ́ òun ló gbélé tí a kọ́ tà. Ó ní:

“Kàkà kí n bẹ́gbàá ọ̀bùn

Má kúkú bí ọ̀kan ṣoṣo ọ̀gá

Ma fi yán aráyé lójú

Ma  róhun gbéraga”

(Ojú Ìwé 7, ìlà 1-4)

Ó tẹ̀ síwájú láti tún jẹ́ ká mọ̀ pé bó bá jẹ́ ọmọ kan ṣoṣo ni ènìyàn bí, tó sì tọ́ ọmọ náà dáadáa, ó sàn ju kéèyàn bí ọmọ kalẹ̀ rẹpẹtẹ lái bójútó wọn lọ. Ó ní:

“Ṣé ọ̀kan ṣoṣo àràbà

Kì í ṣe ẹgbẹ́ ẹgbàá ọ̀súnṣún

Ọmọ tó bá já fáfá kan ṣoṣo

Kìí ṣe ọgbà igba irunbí ọmọ”

(Ojú Ìwé 7, ìlà 5-8)

Akéwì túbọ̀ ṣe é lálàyé fún wa pé ohun ìtìjú àti ẹ̀gàn ńlá ni kí ọmọ dàgbà kó má wúlò jẹ́. Bóyá látàrí àìrí ẹni tọ́jú ẹ̀ láti kékeré tàbí àìgba ẹ̀kọ́. Ó sàn kí irú ọmọ bẹ́ẹ̀ kú léwe tàbí kí wọ́n má wulẹ̀ bí i sáyé rárá ju kó dàgbà tán kó máa ráre kiri.

“Àkúkú-ù-bí sàn ṣé ràdàràdà

Ká kú lọ́mọdé kó yẹ ni

Sàn ju ká dàgbà atọrọjẹ lọ”

( Ojú Ìwé 7, ìlà 9-11)

Kókó ohun tí Akéwì ń fẹ́ ká dìmú ni pé kìí ṣe pé ká bímọ nìkan ni pàtàkì ọmọ, bíkóṣe pé ká tọ́ ọmọ ọ̀hún kí á lè jèrè rẹ̀. Àbíìkọ́ tàbí àkọ́ọ̀gbà, àbámọ̀ ló máa ń dà nígbẹ̀yìn.

Nínú ewì “Ọmọ bẹẹrẹ, òṣì bẹẹrẹ”, akéwì sọ̀rọ̀, ó ní:

“Bí o bímọ tó pọ̀ térùpẹ̀

Bí wọ́n wà láì lọ́gbọ́n

Ọmọ páláńtá lo bí jọ

Ọmọ tí í dẹrú fẹ́ni ẹlẹ́ni

Tí í sì í dòpìjẹ́ fájẹ̀jì

Akótilétà ọmọ ọ̀dọ̀gọ

Ọmọ ṣá-á, ọmọ koríko ni”

(Ojú Ìwé 11, ìlà 1-7)

Àyọ̀lò òkè yìí túbọ̀ fidí kókó ọ̀rọ̀ wa múlẹ̀ nípa ọmọ bíbí. Ṣé ẹni bímọ ọ̀ràn ní í pọ̀n ọ́n. Bọ́mọ́ bá pọ̀ rẹrẹẹrẹ tí wọn kọ̀ wà láì lẹ́kọ̀ọ́, àgbákò burúkú ni wọ́n máa ń kó bá àwọn òbí wọn. Wọn kìí wúlò fún ara wọn débi pé wọn yóò wúlò fún òbí tàbí àwùjọ. Irú u wọn ló ń ṣerú ẹgbẹ́, irú u wọn ló ń kó tilé tà.

Akéwì tún tẹ̀ síwájú láti jẹ́ ká mọ èrè pàtàkì tó wà nínú ká tọ́ ọmọ sọ́nà pẹ̀lú ẹ̀kọ́ tó yè kooro. Ó ní:

“Ṣùgbọ́n bí o bímọ méjì

Bí wọ́n sì lọ́gbọ́n

Bí o sì kọ́ wọn dáradára

Ọmọ tó pé lo bí yẹn

Ọmọ tí í tu ìyá nínú lọ́jọ́ ogbó rẹ̀

Ọmọ tí í so baba ró nílé lóko

Ọmọ tí í ṣẹ̀hìn dòbí

Ọmọ tí í fún ni níyì fún ni lọ́lá

Ọmọ tí í delé de Baba

Bíkú mú u lọ

Olúwa kó fún wa lọ́mọ tó yanjú kerekere"

(Ojú Ìwé 11, ìlà 8-18)

Akéwì tún jẹ́ ká mọ pàtàkì ọmọ bíbí nínú ìgbésí ayé ẹ̀dá pẹ̀lú ohun tó sọ nínú ewì "Pàtàkì Owó Níní àti Ọmọ Bíbí", ó ní:

"Ọmọ ló ṣebi kejì ipò ènìyàn

Orí kó jẹ́ ng bímọ là láyé mi

Ọmọ tó gbọ́n tó gbé làákàyè wọ̀

Ọmọ tó máa ṣẹ̀hìn bí mo bá relé

Bó jénìyàn kan kò bá bímọ láyé

Bó ń ṣe fújà ayé a mẹ́nu sí i

Ẹni tó bímọ púpọ̀ má sìnrègún

Ẹni ọmọ bá sin ló nà ń ṣòbímọ

Orí kó jẹ́ ng bímọ àtàtà o

Ọmọ tó máa ṣẹ̀hìn bí mo bá relé"

(Ojú Ìwé 25-26, ìlà 21-30)

Lóòótọ́ ni ọmọ bíbí ṣe pàtàkì tó sì tún jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ohun tó ń mú ìgbé ayé yẹ ènìyàn; ṣùgbọ́n ká bímọ kalẹ̀ nìkan kọ́ ni à ń sọ bíkòṣe pé ká tó ọmọ náà, kó gbẹ̀kọ́, kó yanrantí, kó sì tún gbẹ̀yìn ẹni; ìyẹn gan ni iyì ibẹ̀. Ṣé ẹni ọmọ sin ló kúkú bímọ.

## Ẹ̀kọ́ Nípa Ewu Ìkóbìnrinjọ.

Ipa tí obìnrin ń kó láwùjọ ò kéré rárá. Bẹ̀rẹ̀ láti inú ilé títí lọ dé gbogboibi tí ẹ̀ka àwùjọ gbilẹ̀ sí, kò sí ibi tí a dé níbẹ̀ tí a ò ní bá obìnrin. Abiyamọ ni wọ́n, alábàárò ni wọ́n, amúlùúdùn àti olùrànlọ́wọ́ ni wọ́n pẹ̀lú; kódà bí a bá sọ pé àwọn gan ni Olódùmarè gbé ìṣàkóso ilé ayé lé lọ́wọ́, a ò jayọ̀ pa.

Ṣùgbọ́n àwọn àgbà bọ̀, wọ́n ní 'Òrìṣà jẹ́ n pé méjì obìnrin ò dénú', èyí ni pé kò sí obìnrin tí inú rẹ̀ máa ń dùn sí i pé kí ọkọ ó fẹ́ obìnrin míràn lé òun, ṣé ilé olórogún ilé ariwo àti ìjà ni, òní ẹjọ́, ọ̀la bìlísì; bí wọ́n ṣe ń gbé wàhálà kaná ni wọn yóò máa sọ ìjọ̀gbọ̀n kalẹ̀ torí ohun míràn sì kọ́, torí àwọn ajowú-yọkọ-lẹ́nu yìí náà ni.

Akéwì yìí fi ewì rẹ̀ tọ́ka àwọn ewu àti ibi tó wà nínú kí ọkùnrin máa fẹ́ obìnrin jọ sílé, ó jẹ́ ká mọ̀ pé ewu ńlá gbáà ni. Ọkùnrin tó bá fẹ́ ní ìbàlẹ̀ ọkàn nínú ilé kó ṣọ́ra fún kíkó obìnrin jọ. Bí wọ́n ṣe dára sí náà ni wọ́n burú sí, bí ó bá mọ ní ẹyọ kan ṣoṣo, ọkùnrin a máa gbádùn wọn torí ibi tí wọ́n dùn mọ nìyẹn, bí wọ́n bá ti ń pé méjì sí mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, ọ̀ràn ńlá ń bọ̀ ó dájú.Nínú ewì "Àwọn Ibi Àṣà Ìkóbìnrinjọ", Akéwì sọ̀rọ̀, ó ní:

"Sàlámọ́tù wà níyẹ̀wù

Sàfú ń bẹ níkùlé

Ẹ̀bùn sì tún ń mí lọ́jà

Tó ń ṣòwò pẹ́rẹ́wú

Ṣé owó tí o ní ni wọ́n ń fẹ́ gbogbo

O jẹ́ ronú wò ọ̀rẹ́ mi

Kí o gbọ́ ohun tí mo fẹ́ bá ọ sọ"

(Ìlà 1-7, Ojú Ìwé 9)

A ó ri pé àwòrán inú ilé kan tí ó kún fún obìnrin ni Akéwì ń fi àyọlò òkè yìí yà sí wa lọ́kàn. Ófi ewì yìí gba àwọn ọkùnrin tí wọ́n ń ṣe irú èyí ní ìmọ̀ràn pé kí wọ́n sọ́ra torí pé owó tí ó pọ̀ lọ́wọ́ wọn bí i ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ lásìkò náà ni ó fẹjú mọ́ àwọAa

Owó sì ń mí lẹ́gbàá-gbọ̀n

Ni obìnrin kò mọ ilé ara í lọ

Ṣùgbọ́n bówó bá ku ogójì lápò

Ọ̀kan a ní inú ń run Ìyá òun nílé

Èkejì a ní orí ń fọ́ baba òun lóko

Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ bẹ̀ẹ̀ títí

Ni gbogbo wọn fi í lọ tán porogodo”

(Ìlà 8-15, Ojú Ìwé 9)

Ibi tó bá tutù ni obìnrin máa ń fẹ́ bà sí. Kìí ṣe gbogbo wọn ni wọ́n ní òye pé ìgbà kan ò lọ bí òréré bẹ̀ẹ̀ ayé ò tọ́ lọ bí ọ̀pá ìbọn. Àwọn ìgbà kan a máa wà to jẹ́ pé nǹkan ò ní fi bẹ̀ẹ̀ ṣe déédé nínú ilé, bó bá ṣèsì wáyé, igí dá ẹyẹ fò ni lọ́dọ̀ obìnrin. Ọwọ́ epo ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn ń bá ọkùnrin lá, nígbà tí gbogbo ẹ̀ bá ń dùn tó ń rọ̀ṣọ̀mù ṣe ló máa ń dàbí ẹni pé wọn ò lẹ́bí tàbí ẹnìkankan tí wọ́n lè sá lọ bá fún ìrànlọ́wọ́ ọkọ wọn, ṣùgbọ́n bówó bá sáfẹ́rẹ́ lọ́wọ́ akọ, abo a máa pòórá bí isó. Ẹni tó fowó kó wọn jọ ló máa jẹ èyí tó jù nínú ìyà. Obìnrin dùn lóòótọ́, ṣùgbọ́n ewu ńlá ń bẹ nínú u kíkó wọn jọ.

“Ṣé owó ló tán lọ́wọ́ oníwá

Ló bá dòṣónú

Owó tán nílé

Baba di pálántà fọmọ

Ṣé ìgbà tí kò sówó mọ́

Làgbà gbékútà ọjà

Tí jagun fi káàyá tẹrí fúnra rẹ̀”

(Ìlà 17-23, Ojú Ìwé 9-10)

Akéwì jẹ́ ká mọ̀ pé ọkùnrin tó bá ní ẹ̀mí ara rẹ̀ ẹ́ lò, tó sì fẹ́ fi ìbàlẹ̀ ọkàn gbé ilé ayé pẹ́, ó yẹ kó ṣọ́ra fún obìnrin. Kò sí iyì kankan nínú ká máa kó obìnrin jọ bí i pàǹtì, kò sérè kankan nínú òwò rẹ̀. Akéwì ní:

“Ẹ jẹ́ ká ronú wò

Ká má tanra wa jẹ

Bí a bá lówó lọ́wọ́

Ká yé é fi káya jọ”

(Ìlà 34-37, Ojú Ìwé 10)

Àwọn ọkùnrin ni akéwì ń báwí níbí yìí. Ó ní tówó bá dé ká fowó ṣe nǹkan míràn tó gidi. Kí a tó fẹ́ obìnrin ká ròó jinlẹ̀ dáadáa, àyàfi ọkùnrin tó bá fẹ́ máa tàn ara rẹ̀ jẹ ni yóò máa fi owó rẹ̀ fẹ́bìnrin káàkiri. Kò sí ohun tí à ń gbá ládùn lára wọn tó lọ títí, ọkùnrin tó bá gbọ́n a máa fètò sí i kó má ba à ṣubú.

Akéwì tún wá gba àwọn ọkùnrin nímọ̀ràn pé kí wọ́n ro ọjọ́ iwájú kí wọ́n tó máa fẹ́ aya kún aya, kí wọ́n ro ọjọ́ ọ̀la kí wọ́n tó máa fi ìyàwó kún ìyàwó torí kò sí irú owó tí èniyàn lè ní láyé bó bá fi ṣòwò obìnrin, oko ìparun ló ń lọ.

“Tàbí ta ní mọ ohun tó ḿbọ̀ níwájú

Tí ó ní tọ́rọ́ lọ́wọ́

Tí ó káya kúnlé káya kúnta?

Tàbí èèló lo ní tí ò ń pè lówó?

Tọ́rọ́ lo ní ni tàbí náírà kan

Tí ó tóhun í ṣe fáya bẹẹrẹ?

Bí o sì tilẹ̀ ní gbìngbìnnìkìn

Ǹjẹ́ o mọ ohun tó ń bọ̀ níwájú

Tí o fi gbogbo ilé káya jọ?

(Ìlà 39-47, Ojú Ìwé 10)

Akéwì tún fi ọ̀rọ̀ ìkóbìnrinjọ yìí ṣe iṣu atẹnumọ́rọ̀ pẹ̀lú ewì rẹ̀ kan tí ó pè ní “Aya bẹẹrẹ ní ń dalé rú”. Ṣé bí alágbẹ̀dẹ̀ bá ń lurin lójú kan, ó níhun tó fẹ́ fi rọ ni. Ó níhun tí Akéwì rí tó fi n fi ọ̀rọ̀ ọ̀hún ṣe kankan là ń ran fádití, ó ní:

“Ṣùgbọ́n ó tún ku ohun míràn

Tí ó yẹ ká rò kíníkíní

Nípa kíkó aya jọ bí a ti ń sọ

Bí owó bá wà mùtúmùtẹ̀ ń kọ́

Nínú ilé tí a gbé káya jọ?

Èyí ń du orí ara rẹ̀

Tọ̀hún ń mú ti ọmọ rẹ̀ gbọ́

Olúkálukú a gba ilé Babaláwo

Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀ ni wọ́n ń di olóògùn

Wọn a gbàjẹ́ wálé

Wọn a máa fínra wọn lápẹ”

(Ìlà 1-11, Ojú Ìwé 12)

Ohun tí Akéwì tún ń fi yé wa pẹ̀lú àyọlò òkè yìí ni pé bí ènìyàn tilẹ̀ lówó lọ́wọ́, tó lọ́lá tó tún kọ́lé rẹpẹtẹ, bó bá fi gbogbo ilé kó aya jọ, a di ilé olórogún, eré e bí ọmọ ẹnìkan ò ṣe ní ga ju ti ẹnìkejì lọ ni gbogbo àwọn obìnrin ọ̀hún a máa sá kiri. Bí wọ́n ṣe ń tọ babaláwo lọ ni wọn yóò máa yalé oníṣègùn àti Adáhunṣe gbogbo kiri tí olúkúlùkù a sì máa wá ọ̀nà tí yóò fi máa roko gbogbo ogún ọkọ sí ọ̀dọ̀ ọmọ tirẹ̀. Òmíràn lè torí rẹ̀ lọ wọ ẹgbẹ́ àjẹ́ tàbí awo òkùnkùn míràn kí ó lè jẹ gàba lórí àwọn ìyàwó yòókù láti gbogbo ohun ìní ọkọ wọn fún ọmọ tirẹ̀ nìkan ṣoṣo. Nígbà tí wàhálà àti ìṣòro tó so mọ́ ọ bá dé, gbogbo owó tí ọkọ ní kò ní lè ká a torí kò ní mọ ibi tí ogún ti wá.

“Èyí kò tọ́, ó yẹ ká rò ó wò kíníkíní

Ká yé ṣohun

Tó ń mú kú wá bọ́mọ ẹni

Ká fàṣà òyìnbó kọ́gbọ́n

Kílu lè tòrò pẹ̀sẹ̀

Káyé dára fún gbogbo wa”

(Ìla 22-27, Ojú Ìwé 12-13)

Gbogbo àwọn ohun tí Akéwì fi là wá lọ́yẹ̀ lórí ewu tó wà nínú kíkó obìnrin jọ ni ó fẹ́ ká tẹ̀lé torí bá à bá dẹ́kun fífa gbùrù rẹ̀, kò ní yé fagbó. Ṣé bọ́ọ̀dẹ̀ ò dùn, bí ìgbẹ́ nìlú ń rí; ilé ọ̀hún la sì ti ń kó ẹ̀ṣọ́ ròde. Bí inú ilé bá tòrò, ìlú a máa wà lálàáfíà, àwùjọ a sì tún máa dùn ún gbé fún gbogbo mùtúmùwà.

## Ipò Pàtàkì Tí Ẹ̀kọ́ Ìwé Wà

Àwọn Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, “Kékeré la ti ń peékan ìrókò, bó bá dàgbà tán apá kìí ká a mọ́”. Akéwì fi èyí ṣe àṣàrò ọ̀rọ̀ fún wa lórí àwọn ọmọdé pẹ̀lú bó ṣe yẹ ká máa fi ẹ̀kọ́ tó dájú tó sì tún yè kooro ró wọn lágbára láti kékeré kí wọ́n ba lè máa rìn nínú rẹ̀ títí wọn yóò fi dàgbà torí àwọn gan ni ọjọ́ ọ̀la àwùjọ wa. Bá a bá wá fẹ̀tẹ̀ sílẹ̀ tí à ń pa làpálàpá, tá a fi ẹ̀kọ́ tó yẹ ká kọ́mọ sílẹ̀ tí à ń ṣafẹ́ kiri, bó pẹ́ bó yá, wọn a máa padà wá di ọmọ burúkú kalẹ̀, wọn a máa da ilé àti ìlú láàmú, wọn a sì máa kó ẹrẹ̀ bá àwùjọ. Nínú ewì “Pàtàkì Ẹ̀kọ́ Fún Ọmọdé”, Akéwì ní:

“Ohun tí a bá jẹ síkùn

Ní í so ẹ̀mí ró

Ohun tí a bá fi kọ́ ọmọ ẹni

Ní í di ogun fún un

Ẹ̀dá tó fi ọmọ sílẹ̀

Láì kọ lọ́gbọ́n

Tó ń kọ́lé, tó sì ń kààsẹ̀ jọ

Kó rántí pé ilé yóò di ilé ẹni ẹlẹ́ni

Ààsẹ̀ yóò di ààsẹ̀ ọmọ ẹlòmíràn

Ogún yóò di ogún ẹbí ẹlẹ́bí gbogbo

Tàbí ta ni kò mọ̀ dájú pé

Ọmọ tí a kò kọ́

Ni yóò gbé ilé tí a kọ́ tà?”

(Ìlà 1-13, Ojú Ìwé 14)

Ohun tí a bá fi kọ́ ọmọ láti kékeré ni yóò mọ lára dàgbà. Ọ̀tọ̀ ni àbíìkọ́, ọ̀tọ̀ sì ni àkọ́ọ̀gbà, ẹ̀kọ́ tó yè kooro fún àwọn ọmọ ni ó máa ń mú àdínkù bá àwọn ìwà pálapàla tí wọ́n máa ń hù bí wọ́n bá dàgbà tán. Ṣé ìgbẹ̀yìn ló máa ń dun olókùú àdá sí, ọmọ tá ò bá kọ́ ni yóò gé ìka abámọ̀ jẹ nígbẹ̀yìn.

“Ẹ jẹ́ ká ronú wò

Fún ìgbẹ̀yìn ọmọ ẹni

Ká kọ́ wọn lọ́gbọ́n

Tó yanjú korokoro”

(Ìlà 21-24, Ojú Ìwé 14)

Nínú ewì “Isẹ́ Ni Òògùn Ìṣẹ́”, Akéwì tún fi pàtàkì ẹ̀kọ́ hàn nígbà tí ó sọ pé:

“Ẹ̀kọ́ sì tún ń sọni í dọ̀gá

Múra kí o kọ́ ọ dáradára

Bí o sì rí ọ̀pọ̀ ènìyàn

Tí wọ́n ń fi ẹ̀kọ́ ṣẹ̀rínrín

Ṣọ́ra kí o má fara wé wọn

Ìyà ń ḿbọ̀ fọ́mọ tí kò gbọ́n

Ẹkún ń bẹ fọ́mọ tó ń sá kiri”

(Ìlà 23-29, Ojú Ìwé 3-4)

Ẹ̀kọ́ dára púpọ̀, ó máa ń gbé ni níyì láwùjọ. Béèyàn bá lẹ́kọ̀ọ́ tó jọjú tó sì tún yè kooro, a máa bá àwọn ọlọ́lá tò pọ̀, a sì tún máa gbé orí ipò ńlá pàṣẹ lọ́jọ́ gbogbo. Akéwì tún wá gbà wá nímọ̀ràn pé bí a bá rẹ́ni tó ń fi ẹ̀kọ́ tàfàlà, tó mú u ní yẹpẹrẹ tí ò tiẹ̀ kọbi ara sí i, ó ní ká má fara wé wọn, ṣé títa ríro là á kọlà, bó bá jinná tán á doge.

Bákan náà, nínú ewì “Pàtàkì Ẹ̀kọ́ Àti Iṣẹ́ Ṣíṣe”, Akéwì jẹ́ ká mọ̀ pé ẹ̀kọ́ ìwé àti iṣé ṣíṣe jọ ń kọ́wọ̀ọ̀rìn ni. Bá a bá ń ṣiṣẹ́, ẹ̀kọ́ là ń kọ́, bá a bá ń ṣiṣẹ́, ẹ̀kọ́ là ń kọ́, bá a bá sì tún ń kàwé, iṣẹ́ là ń ṣe. Ṣé ọ̀lẹ nìkan làáyè ò gbà, ibi gbogbo ló máa ń gba alágbára. Akéwì sọ̀rọ̀, ó ní:

“Dákun múra kí o tún ara rẹ bí, ọ̀rẹ́ mi

Ẹ̀kọ́ ni a fi ń tún ara ẹni bí lọ́jọ́ òní

Iṣẹ́ níí sọni di olówó níbikíbi

Ọmọ tí a kọ́ lẹ́kọ̀ọ́tí ó sì já fáfá

Tó tẹpá mọ́ṣẹ́, tó sì ní ìwà rere

Irú wọn ní í di olókìkí nígbẹ̀hìn wọn”

(Ìlà 19-24, Ojú Ìwé 49)

A tún rí àpẹẹrẹ èyí nínú ewì “Iṣẹ́ Ni Òògùn Ìṣẹ́”, ó ní:

“Iṣẹ́ ni òògùn ìṣẹ́

Múra síṣẹ́ ọ̀rẹ́ mi

Iṣẹ́ là fi ń dẹni gíga

Bí a kò rẹ́ni fẹ̀hìntì

Bí ọ̀lẹ là á rí

Bí a kò rẹ́ni gbẹ́kẹ̀lé

A tẹra mọ́ṣẹ́ ẹni”

(Ìlà 1-7, Ojú Ìwé 3)

Akéwì jẹ́ ká mọ̀ pé béèyàn ò bá rẹ́ni fẹ̀yìntì, fọ̀rọ̀ lọ̀ tàbí dúró tini nígbà ìṣòro, tó bá tẹpá mọ́ṣẹ́ tó sì mọhun tó ń ṣe gidi, dandan ni kó jánà oríire. Bá ò bá rẹ́ni bá

là, a ò gbọdọ̀ fi ọ̀lẹ kún un, ó yẹ kẹ́ni ó tiraka láti ṣiṣẹ́ ni kébi má ba à pa á. Ó tún tẹ̀ síwájú láti jẹ́ ká mọ̀ pé:

"Ohun tí a kò jìyà fún

Ṣé kìí lè tọ́jọ́

Ohun a bá fara ṣiṣẹ́ fún

Ló ń pẹ́ lọ́wọ́ ẹni"

(Ìlà 12-15, Ojú Ìwé 3)

**Pàtàkì Owó Níní Ní Ìgbé Ayé Ẹ̀dá**

Ṣé òṣì ló ń jẹ́ 'Ta ló mọ̀ ọ́ rí', owó ló ń jẹ́ 'Mo bá ọ tan'. Ẹ̀dá tó bá wà láyé tí ò lówó lọ́wọ́, irú wọn kìí lẹ́nu ọ̀rọ̀ láwùjọ. Bí owó bá ń bẹ, ìbàlẹ̀ ọkàn a máa wà torí kò sí ohun náà tí èniyàn fẹ́ ṣe láyé yìí tí kò la owó lọ. Àwọn àgbà bọ̀, wọ́n ní 'Báyé bá ń fẹ́ ọ lónìí, bí o bá lówó lọ́wọ́, ayé a máa fẹ́ ọ lọ́la". Ìyẹn ni pé olówó layé mọ̀, kò sẹ́ni tó ń fẹ́ bá olòṣì èèyàn dòwò pọ̀ nítorí pé ohun tí owó bá ṣe tì ilẹ̀ ló ń gbé. Àwọn ẹlẹ́sìn Kristẹ́nì gan a máa sọ pé 'Owó ni kẹ̀kẹ́ ìhìnrere', nítorí náà owó ṣe kókó ó sì tún ṣe pàtàkì nínú ìgbésí ayé ẹ̀dá. Akéwì fi ìdí kókó ọ̀rọ̀ yìí múlẹ̀ nínú ewì rẹ̀ kan tí ó pè àkọlé rẹ̀ ní "Pàtàkì Owó Níní àti Ọmọ Bíbí", ó ní:

"Ìbànújẹ́ Ajé ṣẹ̀gbọ́n ọ̀gẹ̀yì

Ajé tótó, Ajé tí í sàgbà dèwe

Òun ló mọ́mọdé gorí ipò àgbà

Òun ló ń sàgbà dọmọ kékeré"

(Ìlà 1-4, Ojú Ìwé 25)

Owó ni Akéwì ń sọ̀rọ̀ bá nínú ewì òkè yìí. Ajé ni ó fi ṣe àdàpè rẹ̀. Akéwì jẹ́ ká mọ̀ pé owó a máa gbéni dépò gíga lái wo ti ọmọdé tàbí ọjọ́ orí. Bọ́mọdé bá lówó lọ́wọ́, gbogbo àwọn èniyàn ní wọn yóò máa bu ọlá fún un. Ó tẹ̀ síwájú, ó ní:

"Níjọ́ a re ìgbẹ̀sà ta ń lọ yáwó

Ta ń p'Ajọ́sẹ̀ Ọjánján ní Baba

Ta ń pẹni kò tó ni ní bùrọ̀dá

Ajé tótó, Ajé ṣẹ̀gbọ́n lótitọ́

Ajé tótó, Ajé tí ń sàgbà dèwe

Ajé tótó, Ìbà kí ng lówó lọ́wọ́"

(Ìlà 5-10, Ojú Ìwé 25)

Akéwì jẹ́ ká mọ̀ pé owó a máa jẹ́ ká bu ọlá àti ọ̀wọ̀ fún ẹni tí ò tóni lọ́jọ́ orí. Owó lẹ̀gbọ́n, owó làgbà.

"Òyìnbó tó gorí òkun àtọ̀sà

Ṣówó ló lé wọn jáde àpèkánu

Àpèkánukò ọgbà lẹ́hìn èniyàn

A-tóó-bá-ni-kọ̀yà lọ́jọ́ tó burú

Oníkùmọ̀ ẹ̀dùn tí ń lémọ kágbó

Tótó mo júbà elétí ginrinrin

Ẹni tó júbà rẹ kò ní tòṣì mọ́

Bọ́mọdé júbà fágbà kíbà ó ṣẹ

Ajé tótó, Ajé tí ń sàgbà dèwe

Ajé tótó ìbà rẹ wá bá mi gbé"

(Ìlà 11-20, Ojú Ìwé 25)

Akéwì túbọ̀ fidí rẹ̀ múlẹ̀ fún wa pé kò sẹ́ni tí owó ò lè rán níṣẹ́. Béèyàn bá nílò owó tó sì fẹ́ máa pe owó rán níṣẹ́, dandan ni kó dìde láti mú iṣẹ́ ajé ṣe. Gbogbo ohun tí ẹ̀dá bá gbèrò lọ́kàn ara rẹ̀ láti gbé ṣe láyé, àfi kó siṣẹ́ tọ̀ ọ́ lẹ́yìn kó lè rówó fi ṣe é. Gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni ó fi pàtàkì owó níní hàn nínú ìgbésí ayé ọmọ èniyàn.Nínú ewì rẹ̀ míràn tí ó pè ní "Owó Àpèkánukò", ó ní:

"Ẹni tó fàìríṣẹ́ relé ọ̀rẹ́

Yóò mọ báyé ti í ṣara fún ni

Ọ̀rẹ́ àtàtà kò sí

Bí owó kò bá mà sí lọ́wọ́ mọ́

Ṣé bówó bá tán nílé

Laya ń bú ni lálákọra"

(Ìlà 1-6, Ojú Ìwé 23)

Àyọlò òkè yìí ń fi yé wa pé ibi tí owó bá wà, dandan ni kí gbogbo nǹkan ó máa lọ déédé níbẹ̀. Bówó bá ṣe bí ẹní sáfẹ́rẹ́ lásán, igi dá ẹyẹ fò ni. Àìlówó lọ́wọ́ gan ni baba ìjayà pàápàá jùlọ nínú ìgbéyàwó, bí ọkọ bá lówó lọ́wọ́, tó ń rówó mú kalẹ̀ lásìkò, inú ilé a máa dùn yùngbà, ìyàwó a máa kẹ́ ẹ lójú kẹ́ ẹ nímú, bówó bá tán pẹ́rẹ́n, a máa mú ìkanra dání, a sì máa sọ ọkọ di ẹni yẹpẹrẹ lójú aya. Ṣé ọbẹ̀ tó dùn owó ló pa á.

Akéwì tún tẹ̀ síwájú, ó ní:

"Òṣì níí jẹ́ Ta-ní-mọ̀-ọ́-rí?

Ṣé owó ló ń jẹ́ Mo-bá-ọ-tan

Bùrọ̀dá ìdí-kan

Lówó sọ Adébísí

Gbogbo ayé níí dẹbí

Ẹni owó bá ḿbá jẹ

Tótó fùn-ún! Owó Àpèkánukò

Ẹni tó pọ́rọ̀ rẹ kò tóó pọ́n

Jehínjehín ló ń yọ ọ́ lẹ́nu

Owó tíí sẹ̀gbọ́n dàbúrò

Tó tún ń sọ ẹrú ilé

Dẹni ń gún ni ní kẹ́ṣẹ́ kiri

Ẹni à bá tà ká fi ràtùpà

Tó dẹni àjítannáwò ńkọ́?

Ṣe bówó ló sọ ọ́ dẹni ayé ń pé bọ

Tótó fùn-ún, Ajé ògúnnísọ̀

Ìwọ àjíkí, ìwọ àjíyìn bí Olódùmarè"

(Ìlà 7-23, Ojú Ìwé 23-24)

Bá a bá sọ pé owó dàbí òrìṣà tí àwọn èniyàn ń sìn, a ò jayọ̀ pa. Àti ohun gbogbo, àti gbogbo ohun, owó la fi ń ṣe wọ́n. Owó ń lani ó sì tún ń gbani, ó ń pọ́n ni lé, ó sì tún ń tàbùkù bá ni léyìí tó dálé ìhà tí ó bá kọ sí ni. Bówó bá ń bẹ gbogbo nǹkan a máa lọ déédé, bówó ò bá sí a sì dàbí ìgbà tí ayé yìí ṣámálámálá. Owó la fi ń kọ́lé, owó la fi ń ṣọkọ obìnrin, owó la fi ń rílé gbé pẹ̀lú ìgbádùn tó bùáyà.

"Ẹni tó pé towó ò tó ó pọ́n

Ṣórí burúkú inú

Lólúwaarẹ̀ ń bá kiri

Bùrọ̀dá ń pè ọ́ tàbí o kò gbọ́?

Ṣebí owó níní lọ́wọ́

Ló ń sọ ẹrú dọba fún ni

Òyìnbó tó ń gba ẹ̀hìn ọ̀sà

Tó ń rèé pàgọ́ sí ńkọ́?

Ṣé owó ló mú u wa mọ

Bí tẹ́nun-tẹ́nun ti í họra fún ni

Ajé ògúgúnísọ̀

Ọba Elégbejè àdó!

Ajé tó ń sọ ẹni gbọ́n dẹní gọ̀

Tó sì ń sọ ẹni gọ̀ dẹni gbọ́n

Tàbí àgbà tó ń fọ́nu káà

Láì lówó lọ́wọ́ ń kọ́?

Ṣebí ajá ló ń gbó

Lohun tó ń sọ ńjẹ́ gidi"

(Ìlà 24-41, Ojú Ìwé 24)

Kò síhun tí Akéwì yìí ò forí owó pè tán, béèyàn bá ka ewì yìí jinlẹ̀ gidi, yóò mọ̀ pé pàtàkì ǹlá gbáà ni owó níní jẹ́ ní ìgbésí ayé ẹ̀dá. Owó tó ń sọ àbúrò dẹ̀gbọ́n, tó ń sọ ọmọọ̀ṣẹ́ dọ̀gá, tó ń sọ ẹrú dọba, tó sì tún lè ṣe ìdàkejì gbogbo wọn; béèyàn bá wá sọ pé towó báwo, ó yẹ kí wọn lọ yẹgi fún onítọ̀hún ni.

"Ajé tíí fún ni níyì

Fún ní lọlá

A sọ awo dèké

A sọ ọ̀mọ̀ràn di òpè

A-dùn-ún-ní lọ́wọ́ má dùn-ún-ní lọ́rùn

Ajé ògúgúnísọ̀, ẹgbẹ̀ta obìnrin"

(Ìlà 48-53, Ojú Ìwé 24)

Gbogbo àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí a ṣàlàyé lẹ́kùn-únrẹ́rẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ wọ̀nyí ni ó ṣàfihàn Akéwì gẹ́gẹ́ bí ẹni tí òye àwùjọ yé gidigidi. Ọ̀nà tí ó gbà gbé wọn kalẹ̀ jẹ́ èyí tí ó bá ìgbà mu tí ó sì tún ń ya àwòrán bí àwùjọ ṣe máa ń rí gan ní pàtó láti ìgbà ìwáṣẹ̀ títí di òní. Ó fẹ̀ẹ̀ má sí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ kan èyí tí ó jẹ mọ́ ìṣesí àti ìhùwàsí àwa ẹ̀dá tí Akéwì yìí ò mẹ́nubà nínú àwọn ewì rẹ̀. Èdè inú rẹ̀ yé ni, àlàyé rẹ̀ sì tún ṣe wẹ́kú pẹ̀lú bí àwùjọ ṣe rí àti bí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ṣe máa ń ṣẹlẹ̀ ní pàtó. Wòlíì ni Akéwì yìí. Ó ríran àwùjọ kedere, ó sì fi ewì rẹ̀ jẹ́ isẹ̀ tó bá ìgbà yìí mu tọkàntọkàn débi pé bí ènìyàn bá ń kà àwọn ewì rẹ̀ yìí, dandan ni kó rí tiẹ̀ mu níbẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀kọ́ ìwà àti ìkìlọ̀ tí yóò máa ṣe atọ́nà rẹ̀ lórí bí ènìyàn ṣe lè gbé ìgbé ayé tó dára pẹ́ títí.

**Ìkádìí**

Àfojúsùn iṣẹ́ ìwádìí yìí ni ìṣẹ̀lẹ̀ ajẹmọ́-àwùjọ òde-òní nínú ewì Ọdúnjọ . Òrí kì í balẹ̀ kí ó ma yí nǹkan ni ewì Ọdúnjọ jẹ́ nínú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ lọ́kan-ò-jọ̀kan tí iṣẹ́-ọnà rẹ̀ máa ń dá lé pààpàá rẹ̀. Ewì Ọdúnjọ máa ń tọ́ka sí àwọn ìwà tí ènìyàn máa ń hù tí kò bá ojúmu tó. Ó ń se èyí láti dẹ́kun oríṣìíríṣìí ìwà ìbàjẹ́ nínú àwùjọ. Ìwádìí yìí fi hàn pé, J.F Ọdúnjọ jẹ ọ̀kan lára Akéwì-Akọ̀wé Yorùbá tí ó nífẹ̀ẹ́ sí àwùjọ rẹ̀ dé góńgó. Bákan náà ó ní òye, ìmọ̀ àti ilàkáàyè tí ó péye lórí àṣà àti ìṣẹ àwùjọ rẹ̀, ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé, àwọn ewì rẹ̀ kì í ṣe fún àwùjọ òde-òní nìkan ni ó bámu. Ó wúlò fún àná, òní àti ọjọ́ iwájú fún àwọn ẹ̀dá àwùjọ gbogbo. Ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, bí àwùjọ bá gbé ara lé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ewì pààpàá ewì J.F Ọdúnjọ èyí tí ó kún fún ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, yóò rọrùn láti mú ìdàgbàsókè bá àwùjọ lápapọ̀.

**ÌWÉ-ÌTỌ́KASÍ**


Ọdúnjọ, J.F (1961): *Àkójọpọ̀ Ewì Aládùn*, Lagos: Longman.

Odunjo, J. F. (1963). Aláwìíyé: *Ìwé-kìnnì, fún alakóbèrè ẹ̀kọ́ Yorùbá*: L'ómode àti l'agbà. Lagos: Longmans of Nigeria.

Ọdúnjọ, J.F (1967): "Ewì ní Yorùbá", nínú *OLÓKUN: Ìwé Àtìgbàdégbà ní Èdè Yorùbá*. No. 6, o.i . 13 – 16.

Odunjo, J. F. (1971). *Aláwìíyé: Ìwé-kèjì* (Book 2). Lagos: Longman Nigeria.

Odunjo, J. F. (1973). *Aláwìíyé: Ìwé-kẹta* (Book 3). Lagos: Longman Nigeria.

Odunjo, J. F. (1974.). *Aláwìíyé: Ìwé-kẹrin* (Book 4). Lagos: Longman Nigeria.

Odunjo, J. F. (1974). Aláwìíyé: Ìwé-karùn (Book 5). Lagos: Longman Nigeria.

Odunjo, J. F. (1975). Aláwìíyé: Ìwé-kẹfà (Book 6). Lagos: Longman Nigeria.